23 FEB. 1925

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 136 SATURDAY, FEB. 21, 1925. Fourpence.

**Declared Circulation 1,300 Copies Weekly.**

## White's Golden Female Tonic.

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B. Not obtainable elsewhere.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO **J. F. SICK**
Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elẹjo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Ôlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ om *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—o:—

### I'O BA JẸUN YO, ỌRỌ WEREWERE LO NSỌ.

Isọkusọ ti *Nigerian Pioneer* nsọ lẹnu ọjọ melo sẹhin, kuro ni ohun ti a le f'oju lò dá ; ni koipẹ yi lo da "wòsikà" alùsì kan sinu Iwe-irohin rẹ ti ọjọ kẹfa oşu yi, to ni ẹnikan kọ sinu Iwe-irohin Ilu Oyinbo kan ti o njẹ *African World* ; ti a ba wa'di ẹniti o kọ wosikà na finifini ko ni ju ẹnikan ni ilẹ yi lọ, ti o npe ara rẹ ni nkan gunmọ, ti o si ka ara rẹ si Maleka ti ko ni alẽbù kan rara ri lati igbati iya rẹ ti f'ori rẹ sọ'lẹ ! Ẹniti o ba si tun ka ọrọ kantankantan bi ọrọ ọlọti ti ẹnikan kọ ni iwe pataki sinu *Pioneer* ti ọjọ kẹtala oşu yi yio ri bi ẹniti o kọ'we na ti ngbe Ọbanikoro Oloye gbún awọn Oloye Ẹgbẹ rẹ tókù niti peo sọ pe on nikanşoşo lo ni òye *( wisdom )* julọ ninu awọn Oloye. Kini iba mu akọwe yi şe wọnrọnwọnrọn bi epo gbigbona bayi ? Tabi irufẹ ẹni bẹ fẹ ki a gbagbọ pe Oloye na nbo on l'aşiri şişe egbogi to jire fun ni bi ?

Ko daju bi ẹniti o kọ'we na ri ohun ti a kọ sinu "*Eko Akete*" ti ọjọ 7 oşu yi—iyẹn to ba mọ ede iya rẹ kà—Kiriyo Ajẹbọ miran şa wa ti o le ma şe fãri alailojuti pe on ko mọ ede ilu iya on ni kika—ninu eyiti a wipe Oloye na sọ kã-si-nkan ọrọ nipa ti ipo ti o ni awọn ẹgbẹ on şì wà ati bi Gomina Agba kò ti fi ọla ti o tọ fun wọn ; o da wa loju gbangba pe Oloye na ri Iwe-irohin wa yi ka, ko si ti fi igba kan ranşẹ tabi ki o kọwe si wa pe ohun ti a sọ sinu "*Eko Akete*" na nipa on kù'ná.

Ki *Nigerian Pioneer* lọ fi ti ara rẹ şe ti ara rẹ, ki o lọ gbọ ti oku ti iwe rẹ da ni'lu. abẹ Asia Ọba King ti *England* ni a wa nibi, ki işe abẹ asia Ọba Dahomey.

### ARA LILE NI'PẸKUN ỌRỌ.

A gbọ pe oşe Gomina Agba ni ògógò diẹ ati pe nitorina o dakan lọ si ode Ọyọ fun isinmi ; ara a m'okun o.

### EWO L'AGBALAGBA T'O NŞE LA-NGBA-LA-NGBA ?

Kilo mu sababi a nda Lọya Ọmọtaku Thompson ati ekeji rẹ l'ẹbi ni Kotu awọn Ọlọpa l'Ebute Mẹta ni *Tuesday* ọsẹ yi, tobẹ ti a fi gbọ pe Adajọ itẹ fi bu pọnun meje-abọ ( £7 10 ) fun wọn ni sisan s'apo Ọba fun jijẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa ibẹ fi awọn Lọya mejeji na sun pe nwọn lù wọn l'ẹnu işẹ wọn.

Irufẹ ẹjọ bayi ko yẹ Lọya arara, ohun to yẹ ni lo yẹ ni, okun ọrun ko yẹ adiẹ.

Ọmọ olorò ko ma mba oro jẹ !

---

### BI IKU BA NPA ẸGBẸ'NI AMI ỌRUN A MA SỌ AWỌN TO WA L'AIYE

[ Lati ọwọ Akirimanu.]

Si Oniwe-irohin "*Eko Akete*"

Mo ju ba o,

Bi oninu re enia ba ku gbogbo ẹda a ma kẹdun rẹ nitoripe ni akoko ti o wa laiye o ti şe işẹ rere rẹ larin wọn, şugbọn ti enia buburu ba ku awọn enia a si ma yọ pẹlu ọrọ igbẹhin yi pe :—"a ku tun ku rẹ" bẹ na ni bi enia rere ba si ku nwọn a si ma wipe "oşe ọkunrin lọ, ki Oluwa ma şai fi işẹ rere rẹ han" larin ta'gba tọ'mọde Eko yi ko si ẹniti o le gbọ iku Ọgbẹni Dada Adeşigbin "a to ti le tọ ọkunrin" ti ko ni ke sa a fula pe araba nla kan fi ẹgbẹ le'lẹ ni igboro ilu yi. Ni ọjọ ti gbogbo enia ndu'na lati sin lọ si ile igbẹhin fihan pe iwa

Scouts and friends,

I am sure you will like to know something about our tour in Nigeria; Captain Shepherd and myself left Lagos on the 10th December, 1924. to visit the Scouts in the other parts of Nigeria. There are Scouts at Abeokuta, Ibadan, Oyo, Ijebu Ode, Sapele, Warri, Onitsha, Awka, Enugun, Aba, Port Harcourt, Ikot Ekpene, Itu and Calabar. We heard that there are also Scouts at Bonny and Opobo; but as we are in a hurry to catch the Akabo at Calabar, we could not touch at these two places. I have had a good opportunity, during the tour, of knowing the following places where I went ashore:—From Lagos to Ẹpẹ, Leke, Gbekebọ, Koko, Sapẹlẹ, Warri, Kwalẹ, Agbọr, Isẹlẹ, Asaba, Onitsha and districts, Obunike, Awka, Nsutcha, Enugun, Port Harcourt, Aba, Ikot Ekpene, Itu, Calabar, Bonny Santa Isabel, Fernando Po; Ijebu Ode. The same old places Oyo, Ibadan and Abeokuta. The Scouts in Nigeria are doing their best to do that one 'good turn' every day. Scouting is a great game and we all shall try to play the game and not forgetting to do that one 'good turn' every day.

"For our God, our King, our Country, we will play the Game."

GLADSTONE MACAULAY, A.S.M.,
*Rover Scout.*
Lagos.

## ẸNU TI IGBIN FI BU ORIṢA O TI FIWỌLẸ O.

Si oni iwe Irohin "Eko Akete".

A yọ lati sọ fun gbogbo enia pe aya ẹni ọwọ Revd G. M. Fisher ti Ijọ Christ Church Badagry Mrs (V. I. Fisher) jare Akọwe ọba Mr. Samuel Eben Adeniji nipa ẹjọ ganran Kotu nigbati ẹlẹgiri Adutanfeyin sọ pe obirin Fisher ro jọ tan niwaju Onidajọ agba ti ganran, Lawyer Shyngle, Lawyer Alakija ati Lawyer Kayọde bẹrẹ si fi ibere orişirişi siwaju rẹ o da wọn lohun bi ẹni pe wọn jọ kọ ofin na ni, ọrọ tun pesi jẹ nigbati awọn ẹlẹri Bros. J. A. Morit ati J. A. Seton meji wọnyi ti idi ọrọ Adutanfeyin sọ pe kẹkẹ pa ohun mọ awoko lẹnu. Nigbati o di owurọ ọjọ keji ni Lawyer Shyngle wa bẹ Alufa Fisher ati pe ki wọn ma yọnu mọ. Aşẹ enia ju enia lọ ogo ni fun Ọlọrun.

Lawyer Alakija ati Lawyer Kayode bẹrẹ si bẹ Lawyer Oyinbo funfun ati Lawyer Harrison ti obinrin yi gba; nwọn ni Mr. Adeniji nwa lati bẹbẹ ati lati tuba ki ọrọ rẹ ko ma ba buru siwaju. A dupẹ pe enia Ọlọrun ni enia Ọlọrun njẹ, Alufa Fisher bẹ aya rẹ, o si gba ipẹ na.

Ọgbẹni Shyngle sọ fun Onidajọ pe, enia awọn Mrs Fisher si gba ẹbẹ na. Onidajọ agba wa fi oke le pe Samuel Eben Adeniji ni lati tuba fun Mrs V. I. Fisher o si ni lati fi £15. 15/- gba lori ituba na ati £10. 10/- fun owo irin ẹsẹ Mrs Fisher ati Badagry wa si Eko. "Bi Kiniun ba di ẹlẹru Eranko yio ku ama ṣọ jẹ." A ki Revd and Mrs Fisher ku ajabọ.

Edumare wa lẹhin yin gba gba gba.

EYIOWUAWI.

## EKO HIGH SCHOOL LAGOS.

Results of the Oxford Local Exam. Dec. 1924.

The following *three* candidates, out of the *five* candidates presented for the Oxford Junior Local Exam. 1923, have been successful.

1. ABDUL HAMID FANIMOKUN,
   passed in 5 **subjects:**
   English Language, English History, Religious Knowledge, Latin, Arithmetic.
2. SILVANUS LATUNDE SOARES,
   passed in 5 subjects:
   English Language, Religious Knowledge, Arithmetic, Latin, Mathematics.
3. THOMAS BABINGTON THOMPSON,
   passed in 5 subjects:
   English Language, English History, Religious Knowledge, Arithmetic, Mathematics.

W. B. EUBA,
*Principal.*

Lagos, 10th Feb. 1925.

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi ọ̀wọ̀ Ekuro, Epo ati *Cocoa* ti ku si lọsẹ yi leyi:—

EKURỌ
£15 fun *ton* kan.

EPO.
£29 0 0 fun *ton* kan

COCOA.
£28—£29 fun *ton* kan.

### KANO.

GROUND NUT.
£12 15 0—£13 10 0. fun *ton* kan.

rere ni ẹṣọ enia. Ni igba aiye rẹ o fi gbogbo ohun ini rẹ ṣe iṣẹ rere papa si Ile Ọlọrun si ilu ati awọn ẹbi rẹ pẹlu, mo ṣe akiyesi pe iku rẹ dun ọpọlọpọ ninu awọn ẹgbẹ rẹ nitoripe gbogbo'wọn fa'ju ro korokoro nigbati nwọn ndekun rẹ lọ si ile igbẹhin yara kotopo ti ko ni fereṣe, nitori eyi ni a ṣe wipe " bi iku ba npa ojugba ẹni ami ọrun a ma sọ awọn to wa laiye." Ẹyin ti ẹ nfi ọtẹ ṣe ayọ ẹ ranti pe ọjọ kan nbọ ti a o dẹkun yin sinu yara kotopo yi ti ko ni fereṣe, ba wo ni yio ti ri fun yin ti gbogbo enia ba nwipe "A ku tun ku nyin" nitorina ẹ lọ yipada si iwa rere. Dada Adeṣigbin ku nigbati aiye r'oju ki Oluwa ma ṣai ṣọ awọn ẹbi rẹ toku ki o si tu wọn ninu.

## OMI TITUN DE ẸJA TITUN WỌ'NU RẸ.

Gẹgẹ bi ati nlẹ ẹnu mọ pe odun 1925 yi yio jẹ ọdun ayọ ati inudidun, pẹlu itẹlọrun la fi ri Iwe Irohin ijọ Wẹslẹmu titun ti o jade ka ti ọrọ atata ngbe ara wọn ṣire ninu rẹ. Iwe Irohin yifi wa lọkan balẹ pe nigbakugba ti awọn oniwe Irohin wa ni Eko ba kọlu awọn Ijọ Wẹslẹn ireti wa nipe nisinsinyi ti nwọn ti ni Iwe Irohin yi alaye ọrọ yio ma jade fun itẹlọrun awọn to nka iwe wọn—Nitotọ ati ri oniruru Iwe Irohin ti o dide ti ko fi ọjọ ti ko ni oṣu ti nwọn si ti di ologbe, ṣugbọn eyi ko le ribẹ nitoripe imọlẹ Oluwa nbẹ lara rẹ ki Ọlọrun ma ṣai bu si iṣẹ na fun ire ilu wa yika ati gbogbo agbaiye.

## DARI ẸṢẸ WA JIN WA, GẸGẸ BI A TI NDARI ẸṢẸ JIN ẸNI TO BA ṢẸ WA.

Gẹgẹ bi a ti ṣe ileri fun awọn to ngbadun wa lọsọọsẹ a gbidanwo lati sọ niba ṣoki nipa iwa ojulumọ Karimu Kọtun : lati ẹnu awọn opitan a gbọ pe yio di ọmọ ọdun merinlelogoji ati pe on si ni ọmokunrin keji ti baba rẹ bi ( Buraimoh Kọtun ẹrun re ) ni gẹrẹ to fi ile iwe silẹ o bẹrẹ si ṣowo aṣọ ninu eyiti Ọlọrun ti fi ona rẹ han, nipa iwa rẹ bi ọlọyaya enia awọn ẹgbẹ to ngba bọlu ninu Imale fi ṣe baba ẹgbẹ lẹhin eyi o si tun bọ si ipo baba ẹgbẹ ati alabojuto fun ẹgbẹ awọn Olowolagba. Bi o ti jẹ alabojuto enia to, lẹhin iku Adol. Martins gbogbo ilu gbarajo nwọn si fi jẹ oye Ajiroba fun Ọba wa Eṣugbayi Eleko, ninu eyiti a le wipe o sa gbogbo agbara rẹ lati le fihan pe ipo ọla yi dara fun on. Tani ko mọ pe eṣu le da ija silẹ fun ọmọ pẹlu baba ki nwọn si ma ṣe gbọngan si ra wọn.

Karimu Kotun fẹrẹ mu wa sọ ireti nu nigbati o lọ ko si arin awọn ko ṣe yọ nitoripe a ko ni iru ero bayi si ṣugbọn nisinsinyi to wa ri pe bi o ti wu ki o pẹ to 'Tọba lo ma ṣẹ iyoku diregbe idariji ẹṣẹ to tọ fun gbogbo ilu nitoripe awa papa nfẹ idariji lọdọ Ọlọrun.

Bi a ba ni ka ro bi enu bi enu yio to aṣọ hun ṣugbọn ni ti wa bi enia ti mọ ẹṣẹ rẹ lẹṣẹ o yẹ ki a darijin ṣugbọn yio dun mọ wa ninu bi K. K. ba le ṣe ọgbọn ṣe ọgbọn tun ko awọn ẹgbẹ rẹ jọ ki nwọn si lọ yida ile awọn Oloye pe ọsan to gbe alumọ ki ti tun gbe alumọ bọ K. K. ẹnu ẹni la fi kọ mẹ iwọ logbe tọrọ s'ọwọ ọtun iwọ logbe sisi s'ọwọ osi iwọ lo mọ eyiti o wu wo nibẹ ; ijafara lewu.

## KARIMU KỌTUN.

The above was born at Lagos in the year 1881 and he is the second son of the late Mr. Burai :ah Kotun of Agarawu Street. He started business for himself in Cotton goods immediately after leaving school in 1896, and he proved an exception to the rule that the trade he has since established demonstrates so far that his primary enterprise was well founded. Owing to his unassuming habit he was the first man appointed to the presidentship of a Mohammedan Cricket Club in Lagos in 1907. Furthermore in 1913 he became Managing Director of the Olowolagba Society, and in 1919 through his manly actions he was appointed by the community of Lagos to the very coveted post of Private Secretary to His Highness Prince Esugbayi Eleko in succession to the late Mr. Adolphus Martins. As an experienced and industrious youngman he was fortunate enough since 1910 to be one of the famous sole agents for several firms in Germany—position he is still enjoying till to-day. Next to this he was led away under the influence of unprincipled asso:iates during the so-called Mohammedan Unrest ; as we all know that to err is human he has played his part on the sand as one of the great adventurers, (building that has not solid foundation). He has once visited Hamburg.

Mr. Karimu Kotun is a thorough gentleman but we wish him to make search for the old comrades and we hope that this new year upon which we have entered may bring with it its smiles to him. Good luck, K. K. gallop your horse again to the Central Mosque and play your part and never look behind as Dr. Watt's song :—

Let dogs delight to bark and bite
For God hath made them so ;
Let bears and Lions growl and fight
For 'tis their nature too,

## BI ṢIṢI KO BA PADA LEHIN, ẸNI O YẸ KI A PADA LẸHIN ṢIṢI.

Ni ọse to nbọ *Akirimanu* yio fi idi ọrọ oye Aramu Kandu kan, ti nwon lọ jẹ si idalẹ ti o tun nfẹ bi ige pẹlu adubi ni akoko yi han gbogbo ilu ki Ọlọrun mu ọjọ ro.

Emi ni tinyin nitotọ,
AKIRIMANU.

---


## TO LET

House at No. 14, Alof Street, Lagos containing Parlour and Room, three glass windows, two glass doors, Passages, two Rooms at the back-yard, suitable for married couple, etc.

*Apply to* :—MR. MURITALA ALHAJI, No. 14, Ajanaku Street, or at his shop, 4, Ereko Street, Lagos.

Scouts and friends,

I am sure you will like to know something about our tour in Nigeria; Captain Shepherd and myself left Lagos on the 10th December, 1924, to visit the Scouts in the other parts of Nigeria. There are Scouts at Abeokuta, Ibadan, Oyo, Ijebu Ode, Sapele, Warri, Onitsha, Awka, Enugun, Aba, Port Harcourt, Ikot Ekpene, Itu and Calabar. We heard that there are also Scouts at Bonny and Opobo; but as we are in a hurry to catch the Akabo at Calabar, we could not touch at these two places. I have had a good opportunity, during the tour, of knowing the following places where I went ashore:—From Lagos to Epe, Leke, Gbekebo, Koko, Sapele, Warri, Kwale, Agbor, Isele, Asaba, Onitsha and districts, Obunike, Awka, Nsutcha, Enugun, Port Harcourt, Aba, Ikot Ekpene, Itu, Calabar, Bonny Santa Isabel, Fernando Po; Ijebu Ode. The same old places Oyo, Ibadan and Abeokuta. The Scouts in Nigeria are doing their best to do that one 'good turn' every day. Scouting is a great game and we all shall try to play the game and not forgetting to do that one 'good turn' every day.

"For our God, our King, our Country, we will play the Game."

GLADSTONE MACAULAY, A.S.M.,
*Rover Scout.*
Lagos.

---

## ẸNU TI IGBIN FI BU ORIṢA O TI FIWỌLẸ O.

---

Si oni iwe Irohin " Eko Akete ".

A yọ lati sọ fun gbogbo enia pe aya ẹni ọwọ Revd G. M. Fisher ti Ijọ Christ Church Badagry Mrs ( V. I. Fisher ) jare Akọwe ọba Mr. Samuel Eben Adeniji nipa ẹjọ ganran Kotu nigbati ẹlẹgiri Adutanfeyin sọ pe obirin Fisher ro jọ tan niwaju Onidajọ agba ti ganran, Lawyer Shyngle, Lawyer Alakija ati Lawyer Kayọde bẹrẹ si fi ibere orişirişi siwaju rẹ o da wọn lohun bi ẹni pe wọn jọ kọ ofin na ni, ọrọ tun pesi jẹ nigbati awọn ẹlẹri Bros. J. A. Morit ati J. A. Seton meji wọnyi fi idi ọrọ Adutanfeyin sọ pe kẹkẹ pa ohun mọ awoko lẹnu. Nigbati o di owurọ ọjọ keji ni Lawyer Shyngle wa bẹ Alufa Fisher ati pe ki wọn ma yọnu mọ. Aṣe enia ju enia lọ ogo ni fun Ọlọrun.

Lawyer Alakija ati Lawyer Kayode bẹrẹ si bẹ Lawyer Oyinbo funfun ati Lawyer Harrison ti obinrin yi gba; nwọn ni Mr. Adeniji nwa lati bẹbẹ ati lati tuba ki ọrọ rẹ ko ma ba buru siwaju. A dupẹ pe enia Ọlọrun ni enia Ọlọrun njẹ, Alufa Fisher bẹ aya rẹ, o si gba ipẹ na.

Ogbẹni Shyngle sọ fun Onidajọ pe, enia awọn Mrs Fisher si gba ẹbẹ na. Onidajọ agba wa fi oke le pe Samuel Eben Adeniji ni lati tuba fun Mrs V. I. Fisher o si ni lati fi £15. 15/- gba lori ituba na ati £10. 10/- fun owo irin ẹsẹ Mrs Fisher ati Badagry wa si Eko. "Bi Kiniun ba di ẹlẹru Eranko yio ku ama sọ jẹ." A ki Revd and Mrs Fisher ku ajabọ.

Edumare wa lẹhin yin gba gba gba.

EYIOWUAWI.

---

## EKO HIGH SCHOOL LAGOS.

---

Results of the Oxford Local Exam. Dec. 1924.

The following *three* candidates, out of the *five* candidates presented for the Oxford Junior Local Exam. 1923, have been successful.

1. ABDUL HAMID FANIMOKUN,
passed in 5 subjects:
English Language, English History, Religious Knowledge, Latin, Arithmetic.

2. SILVANUS LATUNDE SOARES,
passed in 5 subjects:
English Language, Religious Knowledge, Arithmetic, Latin, Mathematics.

3. THOMAS BARINGTON THOMPSON,
passed in 5 subjects:
English Language, English History, Religious Knowledge, Arithmetic, Mathematics.

W. B. EUBA,
*Principal.*

Lagos, 10th Feb. 1925.

---

## IGBẸ L'OWO WÀ.

---

### EKO.

Bi òwò Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti ku! si lọsẹ yi leyi:—

EKURỌ
£15 fun *ton* kan.

EPO.
£29 0 0 fun *ton* kan

COCOA.
£28—£29 fun *ton* kan.

---

### KANO.

GROUND NUT.
£12 15 0—£13 10 0. fun *ton* kan.

## This That, and The Other.

*By an Old Crow.*

### A Fairy Dance.

It is naughty enough the action of a group of *fairies* who thought a Fancy Dress Ball is the best form of joy over the Jamiat's Victory and placard notice to that effect.

But it is undoubtedly the greatest heights of audacity on the part of these mysterious "Committee of Gentlemen" not to see the sense in informing the Jamaat Muslims whose name they so cleverly used as Advertisement.

At any rate we hope the disclaimer issued by Mr. Adam I. Animashaun is enough to end this tomfoolery otherwise Ọmọtẹṣọ and Co. may answer to some legal proceedings.

Let us hope that the Jamats will leave no stone unturned in making it very difficult for these Christian adventurers to exploit them henceforward ! ! !

AN OLD CROW.


### White's Golden Male Tonic.

( DOUBLE-STRENGTH )

Whenever a women has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs. Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

SHAKE THE BOTTLE.

ARẸMỌ FUN ỌKUNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nje pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo mejimeji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

**Price ten shillings (10/-) per bottle.**


## MANHOOD.

Lyric by AFOLABI JOHNSON

1. A royal road to manhood lies,
   By way of human mind ;
   A lasting happiness awaits
   Him who the path shall find.

2. Who takes fresh air nutritious food
   The keynote of good health ;
   In whose mind reign pure thoughts and peace
   Emblems of lasting wealth.

3. Who participates day by day
   In pleasures plain and pure ;
   Whose mind o'er body is supreme,
   His manly growth is sure.

4. Who keeps companions separate
   From contact of the proud ;
   Whose conscience as the leading guide,
   Is free from taint of cloud

*Copyright reserved.*


## LOOK OUT

For a new publication entitled :

# Are We Progressing?

*( A Handbook for Lagos Muslims )*

BY

**B. ADE: MUMUNEY**

It contains all that you want to know about The Muslim Community of Lagos from its early days up till the present time not omitting The Muhammedan Crisis.

Book your order to-day at J. A. Fashanu's Store Martins Street, or P.O. Box 241, Lagos.

**Price: Sixpence a copy.**

## WANTED.

A competent Head-master for a secondary school.

*Salary, liberal.*

**Apply** to X in the office of this paper.

## IJỌ WESLEY LI ẸKUN EKO.

### IROHIN IPADE SINỌDU.

Ni *Monday* Ipade Sinọdu tubọ yanju ohun bi melo kan ti o jẹ ọrọ aşiri. A şe idanwo afẹnudahun fun ẹnikan ti a şẹşẹ fẹ gba si ipo oye Alufa ni ọjọ *Tuesday*. A şe idanwo afẹnudahun bẹ fun Ẹni-ọwọ J. C. Cole ti a fẹ gba si Ipo oye kikun. Ni ọjọ keji a tun ye irohin idanwo ọdọdun ti Alufa yi wo lati ọdun mẹrin ti o ti wa ni ipo oye kekere. Lẹhin na ni Alabojuto rẹ damọran pe ki a fi oruko rẹ siwaju Igbimọ Nla ti Ilu Gẹsi ki a si gba aşẹ Igbimọ na lati ba le fi jẹ oye kikun. Alabojuto rẹ atijọ keji, gbogbo awọn Alufa si foh un şọkan lati şe bẹ.

Akọwe Sinọdu ka esi wiwa ti a fi ki Sinọdu atun ti Ijọ Ajaşẹ ati awọn Ijọ ti o wa ni Ilẹ abẹ awọn Faranse, ati iwe ọpẹ lati ọwọ Iyawo I. B. Williams fun idaro ati ibakẹdun awọn Alufa. Ohun pataki ti a şe ni Sinọdu li owurọ ọjọ yi ni afilọ pe Iwe Irohin oşoşu ti Ijọ *Wesley* yio bẹrẹ si i jade li ọsan ọjọ na. Oruko rẹ ni "*The Nigerian Methodist*," eyi ni yio si jẹ ohùn fun awọn Mẹtọdisti ni Ilẹ *Nigeria*. Ewe mẹrinla li o wa ninu akọ jade iwe yi, a o si ta a ni toro-toro, şugbọn a nireti pe bi a ba ta a dã lã a le sọ owo rẹ di kọbọ-mejimeji laipẹ. Pẹlu ayọ ati itara nla ni Ipade fi gba Iwe Irohin yi, nitori o ti pẹ ti a ti nfẹ iru nkan bi eyi, a ni ireti pe awọn enia Ijọ ati awọn ọrẹ yio ra a lọpọlọpọ. Ipade dupẹ lọwọ Ẹni-ọwọ H. W. Stacey, Alakojọ iwe na, ati lọwọ Ọgbẹni P. J. C Thomas, Olotẹ iwe yi fun işe ti nwọn şe ki iwe na to le jade.

Li ọjọ *Thursday* Ẹni-ọwọ W. Eric. Hodges mu imọran wa pe ki a ma şe ipade ẹkọ lẹkan lọdọdun ni Ile-Ẹkọ Kọlẹji, Ibadan fun awọn oluko ti o ti gba Iwe Ẹri Ijọba fun Ipo keji larin ẹgbẹ oluko. Ki awọn Olutọju Ile-ẹkọ kekere to fi oruko awọn oluko ranşẹ fun Iwe Ẹri ipo kini, o tọ ki wọn şakiyesi irohin bi awọn oluko ti şe si ninu ipade ọdọdun yi, bi irohin na ko ba nitẹlọrun, ki nwọn da oruko wọn duro titi awọn oluko na yio le şe bi o ti tọ.

Awọn Aşoju Ijọ wọ gbọgan Sinọdu li akoko ti a yan, Alaga si fi ayọ gba wọn. O sọrọ lori itẹsiwaju ti a ni ninu Ijọ nipa yiyan enia wa si ipade Sinọdu. o si fi ye ipade pe awọn Oyinbo obinrin ti o nko awọn ọmọbirin wa yio ni ipo ni Sinọdu lati ọdun ni lọ.

A fi ọjọ yi soro nipa Işẹ Ẹkọ. A pinnu lati yan Igbimọ Ẹkọ kan fun gbogbo Ijọ Ẹkun Eko, a o si bẹ Igbimọ Ijọ Ilu Gẹsi pe ki nwọn yan Oyinbo Onişẹ-ẹkọ kan fun wa, ki on le şe Olubẹwo gbogbo Ile-ẹkọ Ijọ. Oyinbo na yio şe iranlọwọ fun Ile-ẹkọ ti ko si nlari tobẹ, on ati Igbimọ Ẹkọ ti a o yan yio si d'ọwọ pọ lati mu ire ba awọn oniruru Ile-ẹkọ ti Ijọ. A ni ireti pe Igbimọ Ẹkọ yi yio fi eto si Işẹ-ẹkọ ju ti atẹhinwa lọ. Sinọdu da ọrọ yi ro, nwọn si yan Igbimọ kekere kan lati mu imọran wa fun Sinọdu nipa nkan wọnyi.

A mu ọrọ Ẹkọ Giga ni Ilu Eko wa si Ipade, a si yan Igbimọ kan lati ro ọna ti a le gba lati jẹki Ilẹ Ijọ ti o wa ni Marina ati Opopo nla wulo dada ati pe ki nwọn jihin fun Ipade Sinọdu ẹmirin bi a ti şe le ri aye to fun awọn ọmọ Ile-Ẹkọ Giga.

Lẹhin ipade owurọ awọn Oyinbo Onişẹ-Ọlọrun ti Ijọ yi şe aşe onjẹ fun Alaga, Ẹni-ọwọ Griffin ati aya rẹ ati gbogbo ero Sinọdu. Lẹhin jijẹ, on mimu aye şi silẹ fun biba Alaga ati aya rẹ yọ nitoripe Ọlọrun da ẹmi wọn si pẹ li ẹnu işẹ Rẹ, nitoripe ki o to to ọdun ti o mbọ ọdun işe awọn mejeji ni ilẹ yi yio to ọgọta l'akopọ. Ti dudu ti funfun ti o sọrọ li o fihan pe ifẹran wọn wa lọkan awọn ero Sinọdu.

A fi ipade ti ọsan ro ọna ti a le fi pese fun kikọ enia fun Işẹ-Ọlọrun ju ti atẹhinwa lọ. Irohin Kọlẹji Ibadan fihan pe işẹ ibẹ ngbẹru, şugbọn aye ibi gbigbe ko pọ to. Ọrọ pọ li ọsan ọjọ yi ati li owurọ ọjọ keji, a si wa pinnu pe ki olukuluku Ijọ ki o ro ọna ti o le wọ fun wọn lati fi ko owo jọ fun Kọlẹji na, ati pe ki a fi oye ye awọn enia Ijọ bi anfani Kọlẹji yi ti pọ to fun işẹ Ijọ wa li Ẹkun yi. Dọkita MacWilliam jihin pe nwọn ti yan Dọkita keji ati olutọju alaisan miran si Ilẹ Iwosan ti Ileşa, nwọn yio dide ni Ilu Gẹsi laipẹ. On gba aşẹ Sinọdu lati ba kọ oniruru Ile miran bi mẹrin. Awọn ẹgbẹ ọdọ ti Ijọ *Wesley* ni Ilu Oyinbo yio şe inawo mẹta ninu ile wọnyi, awọn ẹgbẹ awọn ọdọ (*Wesley Guilds*) ti *London* yio şe inawo odindi ọkan lọtọ. Ọgbẹni P. J. C. Thomas sọ bi ohun ti awọn ẹgbẹ na şe ti kun u loju to, a si pinnu pe ki Sinọdu kọwe ọpẹ si awọn ẹgbẹ na.

Ẹni-ọwọ W. F. Mellor damọran pe o yẹ ki a yan ninu awọn onişẹ miran bi awọn oluko kun ero Sinọdu, ati pe o yẹ, ki awọn Ijọ ti o si wa labẹ itọju Mişioni ki o ma yan aşoju wa si ipade pataki yi. Ipade Sinọdu jọhẹn lati şe bẹ bi Igbimọ Ilu Gẹsi ba yọda.

Ẹni-ọwọ Fred Platt sọrọ nipa itẹsiwaju işẹ ati anfani ti o wa ni Ilẹ Ogoni. O gba aşẹ Sinọdu lati bere işẹ titọ awọn onişẹ ni Eie, ati pe ki a yan Oyinbo miran lati ran a lọwọ li ẹkun işẹ ọhun.


**Mr. T. Harding,**

*METHODICAL TAILOR.*

ARALAMỌ WORKSHOP

216, BAMGBOSHE STREET, LAGOS.

**PERFECT FITTING GUARANTEED.**

TERMS :—*CASH WITH ORDER*

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, FEB. 21, 1925.

## AṢORO WỌ BI ẸWU AṢEJU. AṢEJU BABA AṢETẸ.

Irufẹ ọrọ yi lo wa s'ẹnu wa ninu ọsẹ yi nigbati a ri ọrọ Iwe (*Address*) ti a ni Gomina Agba ba awọn Igbimọ Aṣofin sọ l'ẹnu ọjọ diẹ sẹhin.

Ọtalelogọta o le marun ni ewe iwe na jẹ (*265 pages*) ọrọ si pilẹ sibẹ lọpọlọpọ. Ninu rẹ ni Gomina Agba sọ eyiti o ṣẽ sọ ati eyiti ko ṣẽ sọ; o sọ bi Iṣẹ Ijọba ti nlọ dede, o sọ ti ṣiṣi ni Ibadan ti o lọ ṣi ohun iranti awọn Ọmọ Ogun t'o b'ogun lọ, ni ogun a-jakaiye ijelo, o sọ ti iyẹsi ti o ni awọn Alaṣẹ Ilu Hausa fun on ati oniruru ọrọ miran.

Ohun ti o tun sọ ti o dun ni lọpọlọpọ ti a ri ka ninu iwe na ni ti máṣãṣí ọrọ ti o sọ niti Iwe Iyẹsi ti Ilu fi ki kabọ niwọn ọdun kẹta ọ̀hún eyini ni ọjọ kẹdogun oṣu *December 1921*, kosi ẽbu ti ko bu awọn Aṣaju wa tan nipa fifi Iwe Iyẹsi na ṣe ẹyẹ fun u. Ọrọ ibẹrẹ ti o sọ si wọn lara nigbana lo tun lo ninu iwe rẹ ti ọ̀tẹ̀ yi; loju wa eyi ku diẹ ki o to; ohun ti iwa yi fihan ni pe lasan ni Gomina Agba yi npe ara rẹ ni Katoliki, ọmọ lẹhin Kristi, ẹmi idariji ati ẹmi ifojufoda jinna si i gẹgẹ bi Ilà Õrun ti jinna si Iwọ̀ Õrun, kàkà be ẹmi igberaga ẹmi igberaṣanlẹ, ẹmi arank-n, ẹmi ò̀ṣónu, ẹmi aikani si, lo kún ọwọ rẹ tẹtẹ, bi ko ba ṣe bẹ̃ ni, ki lo ri ki o to ma fẹ oku at'ọdun mọdun l'oju wò? Kilo ri ki o to tun mu awọn Aṣaju Ilu bu lẹ̀keji, gẹgẹ bi o ti bu wọn ni iṣaju? Ninu esiẽbu na, o ni Ilu nkọ on ati Ijọba on ni ohun ti awọn ni lati ṣe; Lẹ̀ ẹniti o ba dẹ oju silẹ ki o ri imu, yio ri pe kaka ki Ilu kọ ni ohun ti o ma ṣe ninu Iwe Iyẹsi na, imọran (*suggestions*) lasan ni ilu gbã, ṣugbọn o jọ gaté ko jọ gaté ko fi ẹsẹ mejeji tiro ndan? Ilu kọ Gomina o, Ilu ko kọ Gomina o, a dupẹ pe pupọ ninu gbogbo imọran ti a sọ pe Ilu gba nigbana lo di ohun ti Ijọba papa ti muṣe nisinsinyi.

Ẹ jẹ ki a ni ẹnyin ọkawe wa niran diẹ ninu rẹ:

(1) Ilu sọ ninu Iwe Iyẹsi ti Idunna na pe ki Ijọba din owo ibode ti awọn onişowo nsan lori *Cocoa* ti nwọn fi nṣọwọ si Ilu Ọba ku, ki ò̀wò ba le ma lọ siwaju ju ti atẹhinwa lọ—Ijọba si din ku.

(2) Ilu sọ pe ki Ijọba kọ ile ibugbe fun awọn ti nwọn le fẹ ki ọmọ wọn jẹ *Boarders* ni *King's College* l'Eko nibi; ẹniti o ba lọ si ọdan nisinsinyi yio ri bi Ijọba jẹ ọhẹn si ọrọ na tabi ko jẹ ọhẹn nipa ile fi-ọngbọn-fi-ọngbọn ti Ijọba nkọ nisinsinyi fun imọran na.

(3) Ilu ni ki Ijọba din owo Ọkọ-ile (*Railway*) kù, nitoripe owo ti awọn Olotu ọkọ na ngba lọwọ ero nta wọn l'aiya, ati pe ti o ba dinku ọgọrọ owo ni Ijọba yio ti ibẹ ri—Ijọba sin dinku.

Ẹnyin ti ẹ nwọ ọkọ na lọ si Ibadan nisinsinyi le jẹri si eyi bi irọ ni tabi gasikiya.

(4) Ilu ni ki Ijọba tubọ fẹ Eko nitonpe o fun, Ijọba ko p'ẹkẹ lu ọrọ yi ti Arun Ekute ti ọdun to kọja fi kọ ngọ fun t'olori t'elese wa, nigbana ni Ijọba wa ṣe ṣẹ jigiri lati na aimọye ọkẹ pọun lati fi fẹ Eko ni ọna Yaba, ẹnikẹni ti o ba si lọ si ibẹ gẹgẹbi awa ti lọ l'ọsẹ yi, yio ri ogidigbo iṣẹ ile kikọ ti Ijọba nṣe nibẹ.

Bayi ni ilu fi ebu ti Gomina Agba bu wọn nigbana ṣe osun, ti nwọn fi pa ara.

Kilo tun mu ki o tun ma sọ asọtunsọ ebu na l'ọdunni?

Atilẹ tun ṣakiyesi pe Gomina ko gb'ẹnule ọrọ Eleko ninu Iwe rẹ ti ọdun yi, ṣugbọn ọkan lo da ni loju pe ohun ti Oluwa ma ṣe sidi ọran na, ko fi han ẹnikan, nitorina ki a maṣe banujẹ ju.

Ẹnyin Ọnigbagbọ yio ranti itan ti o wa ninu Bibeli ninu Iwe *Esther* nipa ti *Haman* ati *Mordekai*. Ẹ jare ẹ ba wa wo Iwe *Esther* ori kẹfa bẹrẹ lati ẹsẹ kẹfa de ikẹrinla; Haman ti kĩ fẹ ri Mordekai soju ri, kọ lo tun pada di oloko ẹṣin rẹ nigbẹhingbẹhin?

A ko sọ eyi lati fi ṣata Gomina Agba o. a ko tilẹ tobẹ, ọrọ lo lọ bi owe.

Ohun ti a fẹ ki olukuluku wa mọ ni pe bi Ọlọrun ma sami ẹsẹ, t'emi, tirẹ, tabi ti Gomina Agba Sir Hugh Clifford papa ni, tani ninu wa to le duro?

Ewẹ, a tun bere kilo tete le tẹ-mbẹlu enia bi iwa aṣeju? Bi aṣa owe wa kan "A ṣoro wọ bi ẹwu aṣeju, aṣeju baba aṣetẹ."

Ki Ọlọrun Ọba ko gba ni lọwọ alebu yi.

---

## IGBIMỌ AṢE'LU
## (LEGISLATIVE COUNCIL.)

*Copyright.*

[*Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Ni *Monday* tabi Atini ọsẹ ti o kọja, ni a ṣe Igbimọ ti ilu (*Legislative Council*;) ẹnu kekere kọ ni o si ya ni lati ri wipe, ninu iwe bantabanta ti Gomina sọrọ si (*Governor's Address*,) ọrọ Eleko, eyiti ilu ka si pataki julọ, ko si nibẹ.

Irohin iṣẹ ti Gomina ti nṣe lati igbati o ti gunlẹ si Ebute wa ni ọdun karun ãbọ ni o kun inu iwe na tẹtẹ. Apa kan dara ninu iwe na, apa kan ko dara; ṣugbọn, l'aisi ani-ani, wahala kekere kọ ni Gomina ṣe si iwe rẹ yi!

O di ọjọ miran, ọjọ rere, ki a to le bẹrẹ si fọ ọrọ ti o wa ninu iwe na si wẹwẹ, fun gbogbo ilu, papa fun awọn ọkawe wa ni pataki. Sibẹsibẹ, ọrọ ti a sọ l'ẹsi, lẹhin ti Igbimọ tuka nipa Eleko ati awọn Onifila-funfun, a o tun sọ ọ ni ọsẹ yi, a o si ma wo eyiti Gomina yio ṣe si i ki o to ko ãṣa rẹ kuro larin wa.

### ỌRỌ ELEKO ATI AWỌN ONI-FILA-FUNFUN.

Jakejado ni a fi ka Iwe-eto inawo tabi *Estimate* 1925-1926 na, anu si ṣe ni wipe a ko ri ibiti Ijọba pese owo-sisan fun awọn Onifila-funfun wa. Awọn Onifila-funfun ni o ni ilu; nitorina, ko dara ki Ijọba fi ọrọ wọn da agunla. O yẹ ki Ijọba bẹrẹ si fun ẹnikọkan wọn ni igba pọnwun (£200) li ọdọdun, ki nwọn si ma fi kun owo na diẹdiẹ titi yio fi de ẹdẹgbẹta pọnwun (£500) li ọdọdun.

Bi o tilẹ jẹ Olowonyọ ti a nta ni tọrọ (3d.) ọpa ni nwọn fi nda aṣọ ati Fila-funfun wọn, ipo wọn ni ilu ju ti ẹniti o nde fila alãri, ti o si nwọ Agbada-etu lọ. Ko yẹ ki ọda owo ati ma gbọ bukata ile lasan ma da awọn Oloye wa, bẹni ko yẹ ki ebi inu ma pa awọn pẹlu ẹbi wọn.

Ọrọ Eleko nfẹ atunṣe; l'ai ṣe eyi, aiya ilu ko le balẹ daradara: ati ni iwọn igbati ija nla ti o ti wa li arin awọn Jamani (*Germans*) pẹlu Gẹsi ti le pari, ti nwọn si nṣe ọrẹ pọ nis siyi lẹhin ti t'ọtun-t'osi wọn ti ṣe ara wọn ni ofo ẹmi aimọye ọkẹ enia, l'ai ka ofo dukia ati ohun iṣura iyebiye miran: melomelo ni o ha yẹ ki Ijọba pẹlu Eleko wa ni irẹpọ nisisiyi! Kini Eleko ṣe? Bi Eleko ba tilẹ ṣẹ Ijọba, Dosunmu baba rẹ ti o sọ wipe ilu dun, ki Oyinbo wa j'aiye ha tun ṣẹ Ijọba pẹlu bi? Mo ṣebi ola baba ni ọmọ njẹ, ṣe aiye Ọba ni Ọlọpa njẹ nigbati o wọ ṣokoto kukuru, ti o nhalẹ mọ oniṣokoto gbọrọ?

Ọdunrun pọnwun (£300) pere ti Ijọba nfun Eleko ri, ko to idaji owo (*Duty Pay*) lasan ti Oyinbo miran ngba bi ẹni-akara lori Owo-iṣẹ rẹ: Ile Dosunmu nwo lọ loju Ijọba Gẹsi, bẹni nwọn ko dẹkun ati ma fi owo ilu kọ ile-kun-ile fun Oyinbo ni Ikoyi ati ni ibomiran kakiri. Họwu! Kil' o kuku ṣe? A ha le binu ori, ki a fi fila de idi?

Agbalagba ni Gomina wa, Oni'gbagbọ si ni, o ni ọgbọn lori, o si ni lãkaye pupọ. O fun wa ni anfani nla ati fi enia si Igbimọ; ṣugbọn, bi o ti wu ki o le ṣe ohun rere fun wa to, ti a ba nranti wipe akoko rẹ ni Eleko di ẹlẹha ọsan gangan ni ilu rẹ, akoko rẹ ni a da owo ti ko ju Owo-ẹkọ a-da-wamo ti Ijọba nfun awọn ọmọ ati gbogbo ara ile Dosunmu duro, akoko rẹ ni a ko le da Fila-funfun fun Oniru, Ọjọra, ati awọn Oloye miran, akoko rẹ ni awọn olori buruku Oni'we-irohin nbu Eleko ṣakaṣaka l'ai beru ohunkohun, akoko rẹ ni a ko le ṣe Adamu-oriṣa mọ; ani, ti a ba ranti wipe akoko rẹ ni awọn ọrẹ Eleko di ọta Ijọba, a ko le ṣai bẹ Gomina *Sir* HUGH CLIFFORD, wipe ki o jọwọ fi Eleko si ipo rẹ pada, ki o si gba aṣẹ lati fun u ni ẹgbẹfa pọnwun (£1,200) li ọdọdun, eyiti a o ma fi kun diẹdiẹ titi yio fi de ẹgbã pọnwun (£2,000) fun anfani on ati gbogbo ara ile Dosunmu ti o wa li abẹ itọju ati ãbo rẹ.

Enia Dudu-k' Enia Dudu ti o ba sọ wipe ọrọ ti a sọ yi ko tọ suna, o ku on pẹlu Ọlọrun; o si yẹ ki Gomina mọ wipe, ti Enia Dudu na ba jẹ Oyinbo, ti a si fi Gomina jẹ Ọba Ilu Oyinbo, bẹ gẹgẹ ni oluwarẹ na yio sọ wipe ki a yọ Gomina kuro li oye Ọba. Njẹ inu Gomina papa ha le dun si irufẹ ọdalẹ bẹ?

(*Koi ti pari.*)

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## THE EDITOR'S OBSERVATORY.

### Welcome Home.

Barrister Andrew 'Latunji Thomas son of the late Mr. A. W. Thomas and younger brother of our respected townsman Mr. J. 'Misalewa Thomas, and Mrs. Ayodele Coker and others, arrived from Europe on the Abinsi, on Thursday last.

### Let there be Light!

The members of Bethel Church (African) are dedicating their new Electric Lights to-night at 7.30 p.m. E ku ma'wo o. Rev. A. A. Paddicombe will preach the dedication sermon.

### Debut of a new Monthly.

We receive with thanks a copy of the first Number of a monthly periodical which is sailing on the journalistic sea under the name of *The Common Weal* and is edited by Mrs. Mary D. Howell of London, the magazine bristels with racy articles from the pen of talented writers, not the least of whom is our own Ladipo Solanke B.A., a law student who contributes a very powerful article under the caption of *Nigeria and its Negro Problem* in its pages (pages 8, 9, & 10).

Annual subscription is 15/- payable to the Editor at 5, Brockwell Park Gardens, London S. E., 24.

### Floreat, Tika-Tore Press!!!

We acknowledge with thanks the receipt of a wall-calendar for the present year, from the Manager and Proprietor of the above Press. The Calendar, we note with pleasure, is in its 5th year.

### Many happy returns of the day.

Mr. H. Antus Williams of S. Thomas & Co., attained to his 35th birthday on Thursday last. Many more years of usefulness.

### Mr. J. Oyewole, the Yoruba Story-writer.

Our friend Mr. Oyewole comes out this week with the 3rd edition of his famous story-book *Tenimasunmon-kingbo*: the printing is all that can be desired, and the contents excellent. The book sells at 6d apiece at Tika-Tore Press, and is written in a happy Yoruba style.

---


### ŞABU J. A. SULE—OLOGBE

A fę ki awọn ọrę ati onibara Ologbe J. A. Sule ti Eko ati ni Idalę mọ wipe a şi Şabu rę fun ọja tita, a si din owo ọja na si pọ ọ.

Irin işę kafinta, ti alagbędę ati nkan bi agadangodo, apoti, posi ati ohun ọşọ oniruru ohun ti a kọ le darukọ tan: ya wa wo tirę ki wọn to ra tan ma ję ki ọbọlę ki ọ.

---

When replying advertisers please mention *"Eko Akete."*

## White's Convulsion-Killer.

(FOR BOTH CHILDREN AND ADULTS)

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.,**
**The Reliable Dispensary,**
**41, Offin Road, Lagos**

DIRECTIONS:—For adults one Tablespoonful every halfhour until the fit is gone. As a preventive, one Tablespoonful every morning before food. For Children, one desertspoonful, in the same manner.

"SHAKE THE BOTTLE."

EGBOGI AIPERI.

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe:—Fun Agbalagba, Şibi ti a fi nję iyę meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yio fi oluwa rę silę. Fun ọmọde şibi kọkan bakanna.

Ki Aiperi ma ba şeni:—Fun Agbalagba, ki a ma fi şibi meji-meji tęlę inu lọrọ. Fun ọmọde şibi kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu egbogi na.

PRICE FIVE SHILLINGS (5S) PER BOTTLE

---

# KERE O!

Ę ma foju sọna fun iwe titun ti yio jade laipę yi.

Orukọ ti a le pe e ni

**Iwe Itan Imale Eko**

Ohun ti o bęrę lati ijọ ti ęsin Imale ti wọ ilę yi titi di oni lo wa nibę.

Itan ọrọ ija Imale kun inu rę ati Idajọ Sir Frederick Alan Van der Meulen.

Sisi Sisi ni

Ę lọ fi orukọ silę lọdọ Fashanu ni Ita Martins lọ kankan Şabu Alaji Davies.

OPA TI A GBE LE KA TI ẸHIN LOJU.

ILE AGBE PẸKUN.

Bi o ba nfẹ posi ti o dara fun lilọ nigbati akoko ba de, maṣe gbagbe lati lọ si ọdọ awọn Ọgbẹni wa wọnyi, nibẹ ni o ri oniruru posi ti a ti ṣe lọṣọ fun lilo; owo diẹ ni a nta wọn

Ranti maṣe gbagbe ki Ala jẹ ki ọmọ gbẹhin wa o.

Ile Iṣẹ

J. S. BAMGBOSE
ATI J. SCARIES
*Builders and Contractors.*

No. 161, Igboṣere Road,
Lagos.

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 393

[*Copyright*]

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[Lati ọwọ ATOLUGBOKUN.]

### JUDGMENT SUMMONS.

"Ẹjọ Onigbese"

Niwaju Ọlọla Frederick Alan Van der Meulen ni ọjọ Tuesday ijọ kẹwa oṣu yi February 1925.

P. J. C. THOMAS

*versus*

FLORENTINO SEVERINO.

"Ẹwọn ki pa ọbọ. Ṣugbon ayun ni di."

Ẹjọ yi ni a rohin rẹ ni aipẹ yi ninu iwe irohin wa, nipa ti Ọgbẹni Florentino Severino ti o ngbe 40 Bamgboshe Street ni Eko, eyiti Adajọ paṣẹ wipe ki wọn lọ gbe Severino pamọ si ọgba ẹwọn, nigbati arohin ẹjọ na, ọrọ wa ninu iwe na nipe Ọgbẹni Severino jẹ ẹniti oju ndun sugbọn awa ri wipe ki ṣe wipe oju ndun: I ṣanbam ni oju na fọ, ẹniti oba ri Ọgbẹni yi ni ile ẹjọ nigbati o nsọrọ a ṣebi oriran baibai sugbọn oju na ko si. Ni asiko ẹjọ yi, ojẹ ọran ẹdun fun Ọgbẹni P. J. C. Thomas ati ẹnikẹni to ba wa ni Kotu nigbati Ọgbẹni Severino nsọrọ fanlala wipe ayafi bi oju on ba san ki on to le daba ati san owo, ati wipe ile yi eyi ti oba jẹ ipin ti on ki awọn ọmọ on wa ba lẹhin ti on ba ku. Bi olowo kan ba ti ẹ ya awọn alumongeri ti wọn nṣe "Yara sulu lai" lowo, a ma reti ati gba nitori awọn alumongeri ti oju wọn fọ yi, wọn ko joko kẹtẹlẹ ki wọn da wọ letan, ojo jumọ ni wọn ngbe igba bara ti wọn si nya ojule kiri, nitori ati jẹ ati mu eyiti onipa pupọ.

Ni ijọ kọkandilogun oṣu January 1925 ni ijọba ti gbe Ọgbẹni Severino pamọ si ọgba ẹwọn nitori pe oṣe on ti olodi si ofin eyiti afi sinu iwe irohin wa to kọja. Sugbọn ni ọjọ Tuesday osẹ yi ni Lọya rẹ Ọgbẹni Latunde Johnson ṣe iwe ibura wa (*affidavit*) ti Ọgbẹni Severino ni ki wọn ta ile 40 Bamgboṣe Street ti ojẹ ti on pẹlu aburo on obinrin si meji ni ọgbọgba, ki Ọgbẹni P. J. C. Thomas si ta ipin ti on, nigbati Adajọ ri bayi, o bere ni ọwọ Lọya Taylor ẹniti o jẹ alanu nipa ẹjọ yi bo ba gba bẹ. Lọya Taylor si ni on gba bẹ, lẹhin na ni Adajọ paṣẹ wipe ki wọn da silẹ ni ọgba ẹwọn, bo ba jẹ wipe Ọgbẹni Severino ti gba bayi tẹlẹtẹlẹ ni, ko ni si ogun ọgba ẹwọn ninu ẹjọ yi rara, sugbọn ki tete ye oniburẹdi, odi ọsan gangan, ẹniti oriran nsa fun ẹwọn ka to ni ẹniti ko ri ara ra. Afi eyi ṣe kilọ kilọ fun ẹnyin onigbese to ba ku, ki ẹla ṣọ ara nyin.

## FULL COURT OF APPEAL.

### Ẹjọ Kotu nla awọn Onidajọ Mẹta

*Judgment* " Idajọ "

Niwaju Ọlọla Combe, Van der Meulen ati Tew ni ijọ Wednesday ijọ kọkanla oṣu February 1925.

ALBERT RHODES

*versus*

JOSEPH EGERTON SHYNGLE.

Ẹjọ yi ni eyiti Shyngle ro fun rarẹ niwaju awọn Adajọ mẹta wọnyi. Lọya Latunde Johnson lo wa fun Oyinbo Albert Rhodes ti awọn John Holt & Co., nibi ẹniti Ọlọla Shyngle jẹ lowo ti o si gba aṣẹ lọwọ Onidajọ Tew lati ta oko Shyngle to wa ni Agege fun gbese rẹ, oko yi ni Ọgbẹni Alder Onigbanjo ta ti Ọgbẹni Ade Oshodi ra ni ẹgba pọun ole ẹdẹgbẹta ( £2,500 ) Shyngle ni aṣẹ Adajọ Tew ko tọ sunọ, awọn Adajọ mẹta yi da Shyngle lare ki Rhodes san pọun meje ṣile mẹrindilogun kọbọ mẹjọ owo irin ẹsẹ ( £7. 16. 8. *Costs* )

" *Order should have been served permanent trust Company necersary parties and should have been formed. Appeal allowed. Order set aside. Action remitted to the Court below* "

Oni Koko igbobi o ka re. Lọya Jiga o ka re ọmọ Owa. Adajọ Van der Meulen lo ka idajọ yi.

THERESA SASSIN

*Versus*

NAJIB REZK

*Judgment* " Idajọ "

Ẹjọ yi ni eyiti Adajọ agba Combe da fun obinrin Kọra yi Therasa Sassin ṣugbọn iye owo to pe ẹjọ fun kọ ni Adajọ da fun nigbati ko tẹ lọrun oni on gbe ẹjọ lọ si Apili ti Adajọ mẹta.

Lọya Shyngle ati Thompson lo wa fun *Madam* Sassin Lọya Alakija ati Alakija lo wa fun Najib, Rezk.

Ẹjọ yi ni wọn ro niwaju awọn Adajọ mẹta Ọlọla Van der Meulen, Tew ati Maxwell.

Ni ijọ *Wednesday* ijọ kọkanla oṣu *February 1925* wọn ṣe idajọ yi, niwaju Ọlọla Combe, Van der Meulen ati Tew. Ọgbẹni Tew lo ka iwe idajọ yi. Nwọn si da obinrin yi lare wọn ni ki Najib Rezk san £5,188. ( Ẹgbẹdọgbọn pọun o le ẹwa dinnigba o le meji ) pẹlu Ọgbọn pọun ọgbọn ṣile ( *30 guineas Cost* ) owo irin ẹsẹ.

Ko si aye fun wa lati rohin ti ile ẹjọ Kotu Ọlọpa ninu ọsẹ yi.

## IROHIN ILE ẸJỌ NI EBUTE MẸTA.

Niwaju Adajọ Ọgbẹni H. A. Young

POLICE *versus* LADIPỌ MOTOR DRIVER.

*Charge No. 255/25.*

Ni ọjọ *Thursday* ijọ kejila oṣu yi ni awọn Ọlọpa mu awa *motor* L84 ti ọgbẹni Lọya Montacute Thompson wa fun ẹsun wọnyi.

Ekini:–Ni pe o ko ero to ju mẹrin lo pẹlu ara rẹ ninu *motor*.

Ekeji:–Ni pe o mu panu pẹlẹbẹ alawọ pupa (*yellow plate*) kuro lẹhin *motor* rẹ.

Ẹkẹta:–Ni pe ko fi panu nọmba rẹ kọrun.

Ẹkẹrin:–Ni pe o kọ lati fi iwe *motor* rẹ han (*Vehicle Licence*) nigbati wọn bi lere.

Ẹkarun:–Ni pe o kọ lati fi iwe aṣẹ to fi nwa *motor* han ( *Driving Licence* ).

Lọya Thompson papa oni *motor* lowa ṣe ẹjọ yi fun awa *motor* rẹ oni on ko jẹbi.

" Ika lo ma rojọ. Sugbọn Ika kọ lo ma da ".

Ọgbẹni Pedro lo duro bi agbẹjọ ro Ọba. Ẹleri kini ni Ọmọgbayi nọmba 76. O ni on wa ni ẹnu iṣẹ ni *Church Street* iyẹn ni ẹnu kereni Iddo nibi ti Aṣọgbọn ni ijọ kọkanla oṣu yi ni deda agogo mọkanla arọ, on gbọ fere, on si ri *motor* L84 o nbọ ni ṭọna Iddo on ni ko duro sugbọn awa *motor* yi gba ọna kọrọ ati lọ si Idunmota on si ṣe pẹkirẹki rẹ ni Obun Eko ni bi Ṣọṣi nibi awọn Ọlọpa ma nju wọ fun awọn oni *motor* ibẹ ni *motor* yi gbe duro, on si di mọdigadi rẹ mu, on si ri pe o ko ero mẹfa on papa, ṣi kẹ Panu tuntun ti wọn ni lati so mọ ẹhin *motor* o ti tu kuro (*yellow plate*) eyiti *driver* ni lati fi kọrun ko si ni ọrun rẹ, ko si ọmọde kekere ninu awọn to wọ *motor* rẹ, gende ni gbogbo wọn, ọkunrin mẹrin ati obinrin meji, on bere (*driving licence*) iwe aṣẹ to fi nwa *motor*, o kọ wipe on ko mu wa on wa gbe ẹsẹ lori mọdigadi rẹ, ibẹ ni oni *motor* gbe wa on lọ titi de ti Dọkita Vaughan, o si tun kọ lati mu (*vihicle licence*) iwe *motor* papa wa on ni ki o wa *motor* rẹ ka lọ si *Station* Ọlọpa o si kọ, ibẹ lo gbe bọ silẹ, lo ni ki ọmọ iṣẹ on wa *motor* lọ o tẹte le on de *Station* ibẹ ni on gbe fi ẹsun wọnyi sun.

Ibere Lọya Thompson niba ṣo ki:–Otọ ni Ọlọpa miran wa ni *Church Street* ṣugbọn nigbati on bere lọwọ Ladipọ ko si Ọlọpa kankan ni ọdọ on otọ ni Ọlọpa nọmba C200 lo fun fere iyẹn lo mu on da *motor* duro, on ko si ri pe Ọlọpa C200 ti Ladipọ, on ko si gbọ wipe Ọlọpa C200 ni awọn a mu awọn awa *motor* Lọya Thompson nitori Lọya Thompson lu awọn Ọlọpa ni Ebute Mẹta on ko si le sọ ohun ti ko jẹ ki o ni nọmba *motor* si oruko ẹniti oni *motor* on ko le sọ idi rẹ rara nigbati on ti bere lọwọ Ladipọ fun *Licence* rẹ ti kọ nitorina ni on ṣe mu lọ si ọgba Ọlọpa.

Adajo bere gbolohun kan:–Iyẹn ni bi ọdaran ni awa *motor* L84. Ọlọpa yi ni bẹni.

Ẹleri keji ni Thomas Kafo C200. O ni on wa ni ẹnu iṣẹ ni *Church Street* ni dede agogo mọkanla aro, on ri Ladipọ nwa *motor* L84 bọ lati ọna Iddo o si ko ero (6) mẹfa ọkunrin mẹrin obinrin meji on si fun fere pe Ọlọpa keji ko da duro ibẹ ni Ladipọ gbe gbe *motor* gba ọna Idunmọta, lẹhin na on fun fere pe Ọlọpa keji nọmba 76, ibẹ ni Ọlọpa 76 yi gbe da duro, ki on to sun mọ wọn, Ladipọ awa *motor* ti gbe *motor* ati Ọlọpa 76 lọ si ọna ẹhin ọgba ni ibi ile alarun Dọkita Vaughan, on ri wọn ni sugbọn on ko sun mọ wọn. Ọlọpa 76 mu Ladipọ wa ba on ni ibi ti on gbe wa, Ladipọ bẹrẹ si on bẹ, on wa mu lọ si ọdọ Saji (*Sergeant*), Saji bere *(driving licence)* iwe to fi nwa *motor* ṣugbọn ko le mu jade pelu *(vehicle licence)* iwe ti *motor* papa, o si tun bere panu ti ẹhin *motor (yellow plate)* o ni bawo loti ṣe mu eyi kuro ni ẹhin *motor*, o si nbẹ Saji wipe ko dariji on, o si bere wipe ti ọrun rẹ da, ko le mu jade bakanna lẹhin gbogbo eyi ni Saji wa saji rẹ.

Ibere Thompson. Nigbati iwọ Ọlọpa yi wa ni yara ẹlẹri njẹ o ri Ọlọpa nomba 665 ninu yara ọdọ ẹ ko wa ba ẹ sọrọ. O ni agbẹdọ.

Adajọ bere lọwọ Inspector Pedro bi fereṣe yara ẹlẹri ṣi silẹ, Lẹsẹkanna, Pedro ati ọga rẹ Kester dide lọ wo, Pedro da Adajọ lohun wipe bẹni oṣi silẹ.

Thompson bere. O ni njẹ o gba Ladipọ loju. o ni agbẹdọ, oni njẹ o sọ wipe gbogbo awa *motor* ọga rẹ ni ẹmi mu nigbakugba nitori ọga wọn ba Ọlọpa ja ni Ebutemẹta. O ni nda o.

Njẹ ẹniti ki ṣe Ọlọpa le ba Ọlọpa ja tabi ko lu Ọlọpa ki tẹtẹ ma jẹ oluwa rẹ. O ni tẹtẹ a jẹ. Njẹ ki on bi ọ lere njẹ bi Ọlọpa ba lu ẹnikan njẹ oluwa rẹ le fi iwe ipa mu Ọlọpa. Oni on ko le dahun iyẹn. Eyi ni ipari ọrọ ẹlẹri Ọba

Ladipọ bọ sinu apoti ẹri, o bura, o ni ni ijọ ti wọn mu on, on nbọ ni ati ọna Ebute Mẹta on gba ero mẹrin ati ọmọ ọwọ kan wọn si gbe si ẹsẹ on ko gbowo fun nitori ọmọ ọwọ ni, bi on ti sọkalẹ ni ori Kereni ikan ninu awọn ero ni on fẹ sọ kalẹ ni ọna Idumọta nigbati on gba kọrọ Aṣọgbọn *Street* ero ni on ko bọ silẹ mọ, on a kuku lọ si ita Tinubu, nigbati on ja gbangba Ọbun Eko on gbọ fere Ọlọpa on duro, Ọlọpa meji wa, wọn si bere fun iwe *Motor* ati eyi ti on fi wa *Motor (Vehicle and Driming Licences)* awọn Ọlọpa yi ni 76 ati 200, lẹhin na ni wọn ni on ko ero pupọ oni bẹkọ awọn mirin ni pẹlu ọmọ ọwọ ti gbe lẹsẹ on ko si gba owo fun Ọlọpa C 200 ni fun on ti Ọga yin ṣe ni Ebute Mẹta ti o si ba Ọlọpa ja, ẹyin Dẹrẹba rẹ mẹtẹta ẹyin lẹ ma fi ori fa. Ibẹ lo gbe ni ki on ni sọ ni ọgba Ọlọpa, o ni on ko ni lọ mu nomba on, ibẹ ni Ọlọpa C 76 gbe wọ inu *Motor* lo si joko, on ni wa lọ titi de ile alarun ti Vaughan, ibẹ ni awọn gbe ri Ọlọpa miran, iyẹn si ni ko bọ silẹ, Ọlọpa C 200 lu on.

Ibere Pedro. Njẹ o ti ṣe Ọlọpa ri baun. Bẹni fun ọdun mẹfa. Mo fi panu nọmba mi kọrun, panu ti ẹhin *Motor* si wa ni ara *Motor* on ko yọ kuro.

Ẹlẹri kini fun Ladipọ. Musa bọ sinu apoti o bura. Ero ni on ninu *Motor L84* eyiti Ladipọ nwa ni anọ, on si wa ninu *Motor* nigbati *Motor* duro. Ọmọde ti on gbe wa si Kotu yi lo ṣe ikarun ori ẹsẹ on ni on gbe si, on si fẹ san owo fun ọmọdeyi Ladipọ ni awọn ki gba owo fun ọmọ ọwọ. oju on ni Ọlọpa C 200 gba Ladipọ loju, Ọlọpa C 200 bere lọwọ Ladipọ pe *Licence* rẹ da, Ladipọ ni ka si nkan, Ọlọpa ni oko ju erọ mẹrin lọ, gbogbo awọn bẹrẹ si bẹ, nigbati o npẹ ju lati ni ki awọn to jẹ ero ko dide, ki o mu fun ninu ijoko lo wa, Ọlọpa C 20a ni ki lo ṣe ti okọ fi sinu apọ, Ladipọ ni ibi ti owu on lohun fi si ni yẹn.

Pedro agbẹjọro Ọba ni, ko si ibere.

Thompson ni ọmode yi ẹri kan loje *(The little boy is an exh bit)* Adajo bere lọwọ Musa. Yala bo ri Ọlọpa 665 lo wa 200 sọrọ, sọrọ ni yara ẹlẹri oni bẹ, Adajọ ni ko tọka awọn Ọlọpa ni Kotu Musa si nọ ọwọ pe 665 lo wa ba 200 sọrọ. Eyi wa su Adajọ. Eyi yi ni pe bi ọrọ ti nlọ si 665 la sọ fun 200 on ti 76 nwi ninu apoti ẹri.

Adajọ ni to ba di ijọ *Saturday* ijọ kẹrinla oṣu yi on a da ẹjọ yi, ni arọ ni agogo mẹwa ni Adajọ ka idajọ rẹ o si ni ki Ladipọ ma lọ. Onimọmọ oku orire o.

Ẹnyin ọkawe wa, ajihin gbogbo ẹjọ yi fun yin lati ka, lati ṣe idajo fun ra yin, gẹgẹ bi nkan ti nwalọ si ni Ebute Mẹta.

Emi ni tinyin nitotọ,

ATOLUGBOKUN.


**THANKS FOR SYMPATHY.**

Mr. Akin: Adesigbin on behalf of himself and family begs to tender his sincere thanks to all kind friends here and abroad, who in divers ways have expressed sympathy with them for the irreparable loss the family was called upon to mourn on Sunday 8th instant through the death of his beloved brother, Mr. Dada Adesigbin.

A BOON TO BUSINESS MEN.,

Type-Writers of different Brands e.g. Barlock Monarch, etc. in good condition, on sale.

Prices reasonable to the man in the street.

Terms:—Cash.

Apply to the Editor.

PAUL. I. SAMMUEL.

*Builder and Contractor*

*Residence and Office*:—72 Igboṣere Road Lagos.

*Workshop*:—40 Campble St. Lagos.

**COFFIN ! COFFIN !! COFFIN !!!**

## Preachers for To-morrow.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. ( MORNING )

Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
( EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9 30
EVENING. 5.45—6.30

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | The Curate |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. & 630 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunko |
| 6.30 p.m. | do. | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. H. W. Stacey |
| 7 p.m. | do. | Rev L. R. Potts Johnson |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev S. A. Pearse |
| 7 p.m. | do. | Rev. H. W. Stacey |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do | Rev. S. A. Pearce |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. J. T. A. White |
| 7 p.m. | do. | Bro. W. K. Fafunwa |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. T. D. Shaw |
| 7 p.m. | do. | Bro. A. M. Williams |
| 9 a.m. | Bethel | Bro. A. Abọyade Cole |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. E. O. I. Onitiri |
| 9 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji. |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Salem Church (Ebute Mẹta) | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | |
| | do. | |
| 10. a.m. | African Methodist | Bro. S. A. Fatolu |
| | do. | Bro. A. E. Green |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m. | |
| 6.30 p.m. | Rev. J. R. Williams. |

**(EBENEZER BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | do. |
| 9 a.m. Ararọmi (Baptist) | |
| 6 p.m. | |

**ISOLARIAN BROTHERHOOD.**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Resp'ble Bro' Fagbemi Faj... |
| 7 p.m. | The Founder |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Rev. B. A. Wifunkẹ.

**AHMADIA (ISLAM.)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣode...
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajos... (Central Mosque, Arọloya Street.)

**ZION CONGREGATIONAL**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens. |
| 7 p.m. | do. | do. |

**SALVATION ARMY**

10 a.m. Glover Memorial Hall — Capt. A. A. da Costa
7 p.m — do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Squa...
Wm. C. T. Terrell.

---

### ỌMỌ OKUYANMUYANMU.

" Gbogbo awọn ọmọ Oloye ni Eko ... agbegbe rẹ lo npejọ si Ilupesi Ẹnu-ọ... ni ọ'jọ Satide Satide lati ma gbero ... ti yio jasi idagbasoke ilu wọn.

Ẹnikeji, o ti fi orukọ silẹ nibẹ bẹ? O... kọ ni a fi nwọ ẹgbẹ yi, ọla ni, o ni ... ninu ẹgbẹ yi, niwọn ti o ba ti jẹ ... ninu ọmọ oye wọnyi.

1. Akarigberi
2. Ọgalade
3. Idejọ
4. Ogboni Olorogun

" Ire ilu rẹ ni ki o jẹ ẹdun ero rẹ

JAMES ỌLADIPỌ HO...
DAVID AJE OGUNLA...
*Awọn Akọwe Ẹgb...*

## J. C. VAUGHAN

fi Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ...isole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ...ehin titi di oni.

...ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu ...won onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-...ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ...ti tapoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, ...Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ...ti Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, ...Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa ...okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ...i No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute ...Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati ...Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

...Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass ...Edges, and Removable Lids, on sale at ...Kessler's Establishment, 7, Labinjo ...Lane, Lagos: also Gramophone Records, ...Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt ...attendance. Make a call.

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin ...amọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ...owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, ...Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

### GOOD MARKET

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neurwall 16/18.**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

### Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

**Highly Recommended :**

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sdarkling*

**Per Case**

**33s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, ije, Ẹje Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati oriṣiriṣi arun ... ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

WO'BI ẸNIKEJI.

Oniruru Posi l. o wa fun tita; lọdọ P... I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun me... abọ titi de Pọun mejila ṣile mejila. Ṣ... ri wọn ra ni 40, Campbell Street, le... Ile-isin Ṣọṣi Ebenezer; ati ni No. 7... Igboṣere Road, nitosi *King's College.*

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay.**

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣeṣẹ de ... wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiri... ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ... ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko ... mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ ... idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo ... ti a gbe nta wọn.

***Register Now !***

For the evening classes now forming at the Rose Thomas School of Embroidery, 55, Broad Street, we teach :—

Embroidery, Milinery, Flower Making, Fancy Work, Dress Making.

5 week days, Monday to Friday—from 4 p.m. to 6 p.m.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER